# ỌRỌ NÁÀ DI ARA

**Johannu 1:1-34**

**ẸKỌ 27 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da" (Johannu 1:3).**

**I Ọrọ Naa Ni Ipilẹṣẹ Dida Ayé**

1 Ki aye ki o to wà rárá, ni Ọ̀rọ naa ti wà; nitori Ọrọ naa ni Ọlọrun Ayeraye, Johannu 1:1; 17:5; 1 Johannu 1:1; 5:7; Ifihan 19:13

2 Ọrọ naa wà pẹlu Ọlọrun nigba didá Ọrun ati ayé, Johannu 1:2; Heberu 1:1, 2

3 Ọrọ naa ni Ẹlẹda ohun gbogbo ti ó wà, eyi ti a n rí ati eyi ti a kò rí, Johannu 1:3; Kolosse 1:16; Romu 1:20

**II Ọrọ Naa Ni Iye ati Imọlẹ Araye**

1 Imọlẹ araye naa mọlẹ ninu okunkun ti ẹmi; okunkun naa kò si bori rẹ, Johannu 1:4, 5; 3:19; 1 Johannu 1:5, 6; 2 Timoteu 1:10

2 Iṣẹ-iranṣẹ Johannu Baptisti ni lati ṣe ẹlẹri Imọlẹ naa, Johannu 1:6-8; Isaiah 40:3-5

3 Ọrọ naa ni Imọlẹ otitọ́, ti o n tàn imọlẹ fun olukuluku eniyan ti o wá si ayé, Johannu 1:9; 8:12; Matteu 4:16

**III Ọrọ Naa Di Ara Nigba Ti A Bí Jesu**

1 O wà ninu ayé ti o dá, ṣugbọn awọn ti Rẹ̀ paapaa kò mọ Ọn, Johannu 1:10, 11; Matteu 1:23; Isaiah 1:3; Efesu 4:18

2 Ṣugbọn awọn ti o gbà A gbọ́ ni a tunbi ti a si sọ di ọmọ Ọlọrun, Johannu 1:12, 13; 3:3; Filippi 2:15; 1 Johannu 3:1

3 Ọrọ naa di ara nigba ti awọn angẹli kede ibi Rẹ̀ ni Bẹtlẹhẹmu, Johannu 1:14; Matteu 1:23; Luku 2:10, 11

**IV Ẹri Johannu Nipa Ọrọ Naa Ti O Di Ara**

1 Ẹni ti o de lẹyin Johannu pọ ju u (Johannu) lọ, nitori o ti wà ṣaaju rẹ̀, Johannu 1:15; 3:30

2 Mose ni olufunni ni Ofin; ṣugbọn Jesu Kristi ni Olufunni ni Iyè, Johannu 1:16, 17; 11:25; 1 Kọrinti 15:45

3 Ọrọ naa ni ifarahan Ọlọrun fun eniyan – Aworan Oun tikara Rẹ̀, Johannu 1:18; 14:9; Heberu 1:3

**V Ẹri Johannu Fun Awọn Ju**

1 Iwadii wọn: Njẹ iwọ ni Kristi naa? Elijah ni ọ bí? Wolii nì? Johannu 1:19-22; Malaki 4:5, 6

2 Kikọ jalẹ Johannu ati Ijẹwọ rẹ̀: "Emi li ohùn ẹni ti nkigbe ni ijù" Johannu 1:23; Luku 1:17; 16:16

3 Ẹri Johannu pe oun n fi omi ṣe iribọmi ṣugbọn Kristi n fi Ẹmi mimọ́ wọ ni, Johannu 1:24-38; Matteu 3:11

**VI Ẹri Johannu si Iribọmi Jesu**

1 Ẹri ti o jẹ́ nigba ti Jesu fi ara hàn, "Wò o, Ọdọ-agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ!" Johannu 1:29-31; Matteu 1:21

2 Lakoko iribọmi Jesu, Johannu ri Ẹmi n sọkalẹ bi adaba, Johannu 1:32, 33; Isaiah 61:1; Luku 4:18-21

3 Bi o si ti gbọ́ tẹlẹ, Johannu jẹ́ ẹri pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun, Johannu 1:34; Heberu 7:3

## ALAYE

A mọ Ihinrere Johannu nipa èdè ti o yé ni yekeyeke ti o lò, sibẹ ninu ẹsẹ ti o bẹ̀rẹ iwe yii, ayanfẹ ọmọ-ẹyin yii, ti o maa n gbé ori rẹ̀ lé ookan àya Oluwa rẹ̀, mu ni lọ sinu giga ati jijin ti o wà ninu Kristi ti o kọja oye eniyan.

"Li àtetekọṣe li Ọ̀rọ wà, Ọ̀rọ si wà pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si li Ọ̀rọ na." Ọmọ-ọwọ ti a bí ni ibujẹ ẹran ni Bẹtlẹhẹmu ni alẹ ọjọ naa ti a kò le gbagbe, Ẹni ti o dagba, Ẹni ti Johannu ati awọn ọmọ-ẹyin miiran ba rìn, ti wọn si jumọ sọ̀rọ -- ara Galili yii, ọmọ gbẹnagbẹna – ki kika akoko to bẹ̀rẹ, ki Ọrun ati aye to wà, Oun ti wà pẹlu Ọlọrun. Ọlọrun ni Oun i ṣe! Oun ni Ẹni ti O wi pe ki ayé wà nipa ọ̀rọ agbara Rẹ̀. Awọn itanna, igi, oke kékèké ati nla, òkun ati ilẹ̀, gbogbo wọn jẹ́ iṣẹ́ ọwọ Rẹ̀. Nibi kan rekọja oorun, oṣupa ati irawọ, O gunwa lori itẹ ninu ogo ti O ni pẹlu Baba (Johannu 17:5). Ṣugbọn akoko naa de ti O fi itẹ naa silẹ̀. Ki ni ṣe ti O fi i silẹ? Lati wá sinu aye ìṣẹ́ yii, ki i ṣe fun ohun miiran bi ko ṣe ki o ba a le gbà awọn eniyan ti o ti nù là. "Ọmọ-enia de lati wá awọn ti o nù kiri, ati lati gbà wọn là." "Bi on ti jẹ ọlọ̀rọ̀ rí, ṣugbọn nitori nyin, o di talaka, ki a le sọ nyin di ọlọ̀rọ̀ nipa aini rẹ̀."

Ohun ti a pe ni **Ọrọ** ninu ori iwe yii jẹ itumọ lati inu ède miiran ti a n pe ni **Logos** ti o ni itumọ ti o jinlẹ ju ọ̀rọ lasan lọ.

Itumọ **Logos** jinlẹ ju ọ̀rọ ti a sọ lẹnu tabi ti a kọ silẹ lọ. Bi o ti wu ki o ri, Johannu kò ṣi ède naa lo rárá. Kò sọrọ nipa ẹlomiran bi ko ṣe Jesu Kristi (Johannu 1:14), Ọmọ Ọlọrun lati ayeraye (Johannu 17:5). Ẹnikeji Mẹtalọkan (1 Johannu 5:7).

Awọn wolii igbaani jiṣẹ ti Ọlọrun rán wọn, ṣugbọn wiwá Jesu ju iṣẹ ti a ran An lọ. Gbogbo wa ni a mọ Johannu 3:16 daadaa: "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun." Ajihinrere kan ti wi pe: "Iṣẹ ifẹ ti Ọlọrun rán si ayé yii gan an ni Ọmọ bibi Rẹ̀ kan ṣoṣo." A le sọ pe ni tootọ Oun gan an ni **Iṣẹ** naa ti awọn wolii jẹ́; nitori gbogbo wọn lati ọdọ Mose delẹ tọka si I. A le ka Abrahamu patriaki paapaa si ọ̀kan ninu wọn, nitori Oluwa sọ nipa rẹ̀ pe, "Abrahamu baba nyin yọ̀ lati ri ọjọ mi, o si ri i, o si yọ̀." **Pataki** ohun ti ofin, awọn wolii ati Orin Dafidi tẹnu mọ́ ni nipa Messia ti n bọ̀. Apọsteli Paulu sọ nipa ọjọ Rẹ̀ pẹlu: "Ọlọrun, ẹni, ni igba pupọ̀ ati li onirũru ọna, ti o ti ipa awọn woli ba awọn baba sọ̀rọ nigbãni, ni ikẹhin ọjọ wọnyi o ti ipasẹ Ọmọ rẹ̀ ba wa sọ̀rọ, ẹniti o fi ṣe ajogun ohun gbogbo, nipasẹ ẹniti o dá awọn aiye pẹlu" (Heberu 1:1, 2). Jesu Kristi ni iṣẹ́ ti Ọlọrun rán si ayé, Ẹni ti i ṣe **Ọrọ** ti Johannu kọwe nipa Rẹ̀. Ọlọrun si paṣẹ fun wa lati gbọ́ Ọrọ Rẹ̀; "Eyiyi li ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi; ẹ mã gbọ́ tirẹ̀."

Iye ni Jesu Kristi i ṣe pẹlu. "Ninu rẹ̀ ni ìye wà; ìye na si ni imọlẹ araiye" (Johannu 1:4). Jesu sọ fun Tọmasi oniyemeji pe, "Emi li ọ̀na, otitọ ati iye." O sọ fun Marta ninu ibinujẹ rẹ pe, "Emi ni ajinde ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, yio yè." Fun awọn ọpọ eniyan ni o wi pe, "Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o ni iye ti kò nipẹkun, on kì yio si wá si idajọ; ṣugbọn o ti ré ikú kọja bọ si ìye."

Ohun ti Jesu Kristi mu wá si ayé yii ju ẹsin tabi ẹ̀kọ́ tabi eto igbesi-aye Onigbagbọ́ lọ. Leke gbogbo rẹ̀, O wá lati fi ara Rẹ̀ ṣe ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ, ki araye ba le ti ipasẹ Rẹ̀ ni **Iye,** ki wọn si le ni in lọpọlọpọ. Awọn ẹ̀kọ́ Jesu pé, o si mọ́, o n yí ẹri-ọkàn eniyan pada si otitọ. Odiwọn igbesi-ayé Onigbagbọ́ ti o fi lelẹ ga, o si n rọ olukuluku ọkàn lati gbé igbesi-ayé giga bẹẹ gẹgẹ. Ṣugbọn kò si ẹkọ, tabi odiwọn Onigbagbọ́, tabi eto igbesi-aye ti a gbe kalẹ ti o le sọ ẹni ti o kú ninu ẹ̀ṣẹ ati aiṣedeedee di alaaye. Ohun ti araye n fẹ ni Kristi, Ẹni ti I ṣe **Ajinde** ati **Iye, Ọrọ** naa ti O ti wà pẹ̀lu Ọlọrun, ti I ṣe Ọlọrun.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni Johannu n tọka si nigba ti o wi pe "Li àtetekọṣe li Ọ̀rọ wà?"

2 Ẹsẹ wo ninu ori iwe yii ni o fi ẹni ti o n tọka si hàn?

3 Awọn ẹsẹ wo ninu awọn iwe Johannu miiran ni o tọka si otitọ nla yii?

4 Ki ni kókó ọ̀rọ awọn wolii majẹmu laelae?

5 Ta ni Ofin, awọn Wolii, ati Orin Dafidi n tọka si?

6 Ki ni iyatọ laaarin iṣẹ-iranṣẹ Mose ati iṣẹ-iranṣẹ ti Kristi si ayé yii?

7 Nigba ti Johannu wi pe "Ọ̀rọ na si di ara," ta ni ẹni ti o tọka si? Ọjọ nla wo si ni ọ̀rọ naa tọka si?

8 Lẹyin igba ti o fi hàn pe Jesu Kristi ni Ọ̀rọ naa, awọn otitọ nla miiran wo ni Johannu fi hàn nihin nipa Ẹni ti Jesu I ṣe?

9 Ta ni Johannu tọka si nigba ti o wi pe, "Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo?"

10 Sọ ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun meji ti o fi otitọ ni hàn pe "nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo."

11 Ki ni iṣẹ-iranṣẹ Johannu Baptisti nipa Jesu Kristi?

12 Sọ gbolohun ọrọ Johannu Baptisti kan ti o fi hàn pe Jesu wá lati fi ara Rẹ̀ ṣe ẹbọ.